# NÀÌJÍRÍÀ | NIGERIA

## USCIRF– RECOMMENDED FOR COUNTRIES OF PARTICULAR CONCERN (CPC)

Àjọ orílẹ̀-èdè Amẹ́ríkà lórí Òmìnira Ẹ̀sìn Lágbàáyé (USCIRF) jẹ́ àjọ èyítí ó dá dúró, tí kò ṣe òṣèlú tí ìjọba àpapọ̀ orílẹ̀-èdè Amẹ́ríkà tí ó ń bójútó ẹ̀tọ́ sí òmìnira ẹ̀sìn tàbí ìgbàgbọ ní ilẹ̀ òkèèrè l'ágbàyé. Tí a ṣẹ̀dá nípa Òfin Àjọ Òmìnira Ẹ̀sìn Lágbàáye International Religious Freedom Act (IRFA)] ti ọdún 1998, USCIRF ń lo àwọn òṣùwọ̀n ti àgbáyé láti ṣe àbójútó àwọn ìtàpásí òmìnira ẹ̀sìn tàbí ìgbàgbọ ní ilẹ̀ òkèèrè tí wọ́n sì ń gba ààrẹ, akọ̀wé ìpínlẹ̀, àti Aṣòfin nímọ̀ràn.  USCIRF jẹ́ àjọ tí ó dá dúró tí ó sì dáyàtọ̀ gedegbe sí Ilé-iṣẹ̀ Ilẹ̀-òkèèrè ti orílẹ̀-èdè Amẹ́ríkà ( U.S. Department of State). Ìjábọ̀ Ọlọ́dọọdún ti ọdún 2021 dúró fún àpapọ̀ iṣẹ́ tí ọdún kan láti ọwọ́ Àwọn alákòóso iṣẹ́ àti àwọn òṣìṣẹ́ akọ́ṣẹ́mọṣẹ́ láti ṣe àkọsílẹ̀ àwọn ìwàkiwà tí ó wà nílẹ̀ àti láti dábàá òfin àwọn àmọ̀ràn èyítí ó dádúró fún ìjọba orílẹ̀-èdè Amẹ́ríkà. Ìjábọ̀ Ọlọ́dọọdún ti ọdún 2021 wà fún àkókò láti Oṣù kinni ọdún 2020 títí dé Oṣù kejìlá ọdún 2020, bí ó tilẹ̀ jẹ́ wípé ní àwọn ipò kan a ménuba àwọn ìṣẹ̀lẹ̀ kan tí ó ṣe pàtàkì èyítí ó wáyé ṣáájú tàbí lẹ̀yìn àkókò yìí.  Fún àlàyé síwájú si nípa USCIRF, wo ààyè lórí ayélujára nibí, tàbí kí o kànsí USCIRF tààrà ní 202-523-3240.

## KÓKÓ ÌWÁDÌÍ

Ní ọdún 2020, ipò òmìnira nípa ti ẹ̀sìn ní Nàìjíríà ti bàjẹ́ si, ní èyítí àti ìjọba àtí àwọn olùkópa tí kò ní àtìlẹyìn ìlú nínú wu àwọn ìwà ìtàpásí ẹ̀tọ́ òmìnira ẹ̀sìn àti ìgbàgbọ́ tí ó hàn kedere. Láìkà bíi òfin Nàìjíríà ṣe ńdáàbòbò òmìnira ẹ̀sìn àti ìgbàgbọ́ sí, àwọn ọmọ ìlú Nàìjíríà kojú ìwà-ipá láti ọwọ́ àwọn mùsùlùmí alákatakítí àti àwọn olùkópa mìírán tí kò ní àtìlẹyìn ìlú nínú, àti pẹ̀lú ẹlámẹ̀mẹyà, títi ni mọ́lé láìní-ìdí, àti àwọn ìdájọ́ ikú fún sísọ̀rọ̀ òdì láti ọwọ́ àwọn aláṣẹ ìlú.

Àwọn ilé-ẹjọ́ Shari'a tí ìlú fọwọ́sí ṣe àwọn ìdájọ́ tí ó burú jáì lórí ọ̀pọ̀lọpọ̀ àwọn ènìyàn tí a dá lẹ́bi ẹ̀sùn sísọ̀rọ̀ òdì, èyítí ó ní dídájọ́ ikú fún akorin Yahaya Sharif-Aminu omo odún méjìlélógún (22) nínú, bí ó tilẹ̀ jẹ́ wípé ilé-ẹjọ́ gíga kan wípé kí a tún ẹjọ́ Sharif-Aminu dá. Àwọn aláṣẹ ìjọba tún mú gbajúgbajà ajà fún ẹ̀tọ́ nípa ti ìlànà àbójútó ẹ̀dá ènìyàn Mubarak Bala, ní bí a ṣe jábọ̀, fún ohun tí ó níiṣe pẹ̀lú fífí àwọn ìgbàgbọ́ rẹ̀ nípa ti ìlànà àbójútó ẹ̀dá ènìyàn hàn lórí òpó ìdọ́rẹ̀ẹ́. Bala ńtẹ̀síwájú láti wà ní àhámọ́ láì gbé e lọ sí ilé-ẹjọ́, tí àwọn aláṣẹ sì dínàmọ́ rírí ààyè rẹ̀ sí ẹgbẹ́ àgbẹjọ́rò rẹ̀.

Àwọn ẹgbẹ́ alákatakítí mùsùlùmí ní Nàìjíríà ńtẹ̀síwájú láti tàpá sí òmìnira ẹ̀sìn ní ilà-oòrùn àríwá ti wọ́n tún tàn dé àwọn ìpín kan ní ìwọ́-oòrùn àríwá orílẹ̀-èdè náà. Àwọn ikọ̀ Boko Haram àti Islamic State in West Africa Province (ISWAP) ti jí ọ̀pọ̀lọpọ̀ àwọn ènìyàn gbé tí wọ́n sì ti pa wọ́n látàrí àwọn ìgbàgbọ́ wọn nípa ẹ̀sìn. Àwọn ọmọ-ìjà Boko Haram bẹ́ alága agbègbè kan lórí ti àjọ Onígbàgbọ́ ti Nàìjíríà [Christian Association of Nigeria (CAN)] ní Ìpínlẹ̀ Adamawa nítorí ó kọ̀ láti sẹ́ ìgbàgbọ́ rẹ̀, nígbàtí àwọn ọmọ-ìjà ISWAP pa àwọn òsìsé arannilówó márùn-ún gẹ́gẹ́ bíi ìkìlọ̀ sí "gbogbo àwọn ti àwọn kèfèrí ńlò láti ṣe àyípadà àwọn Mùsùlùmí sí ẹlẹ́sìn Kristiẹni." Àwọn ọmọ ogun ijìhádì tún ṣe ọ̀pọ̀lọpọ̀ àwọn ìkọlù ní àwọn ayẹyẹ ẹ̀sìn: ní Oṣù karùn-ún wọ́n kolu àwọn ara ìlú tí wọ́n ń gbáradì láti ṣínu àwẹ̀ Ramadan wọn, tí wọ́n pa àwọn ènìyàn ogún (20), àti ní Oṣù keje wọ́n kolu àwọn olùgbé ìlú kan tí wọ́n ńkórajọpọ̀ láti ṣe àjọyọ̀ Eid al-Adha ní Maiduguri.

Ní ààrín gbùngbùn orílẹ̀-èdè náà, àwọn ẹgbẹ́ mìírán tí kò ní àtìlẹyìn ìlú tí wọ́n dira ogun tún kọlu àwọn ilé ìjọ́sìn, àwọn ayẹyẹ ẹ̀sìn, àti àwọn olórí ẹ̀sìn. Àwọn àwùjọ Kristiẹni ni a kọlù gan ní ààrin gbùngbùn orílẹ̀-èdè (Middle Belt), nípasẹ̀ àwọn ẹgbẹ́ tí kò ní àtìlẹyìn ìlú èyítí ó dira ogun tí wọ́n sí kọlu ó kéré jù Sóòsì mókànlá (11) àti àwon ayeye Kristieni. Àwọn ènìyàn tí wọ́n ye ìkọlù ti jábọ̀ wípé àwọn ẹgbẹ́ tí wọ́n dira ogun tí wọ́n ní àsopọ̀ pẹ̀lú Fulani lo ìtànkálẹ̀ ẹ̀sìn nígbàtí wọ́n ṣe onírúurú ìkọlù ní àwọn ìlú tí Kristiẹni pọ̀ sí ní Ìpínlẹ̀ Kaduna. A tún jábọ̀ wípé àwọn ajínigbé mọ̀ómọ̀ kolu àwon Kristieni fún jíjínigbé àti ìpànìyàn. Ìjọba Nàìjíríà kùnà láti ṣe ìwádìí àwọn ìkọlù wọ̀nyìí nígbàgbogbo kí wọ́n sì ṣe ìdájọ́ àwọn tí ó ṣeé, èyítí ó ńṣe àpẹ̀júwe ìpele ìṣòro nípa àìbíkítà àwọn òṣìṣẹ́ ìlú.

## ÀWỌN ÌMỌ̀RÀN FÚN ÌJỌBA AMẸ́RÍKÀ

- Tún Nàìjíríà pè gẹ́gẹ́ bíi "orílẹ̀-èdè tí a ní àìbàlẹ̀-ọkàn rípa rẹ̀," tàbí CPC, fún lílọ́wọ́sí tàbí fífi ara da ní tẹ̀le-n-tẹ̀lé ìtàpásí òmìnira ẹ̀sìn, èyí tí ó ń lọ lọ́wọ́lọ́wọ́, tí kò dára tí ó farahàn kedere, gẹ́gẹ́ bi a ṣe túmọ̀ rẹ̀ nípasẹ̀ Òfin Àjọ́ Òmìnira nípa ẹ̀sìn (IRFA),, àti láti tẹ̀síwájú láti tún pe Boko Haram àti láti pe ISWAP gẹ́gẹ́ bíi "àjọ tí a ní àìbàlẹ̀-ọkàn rípa rẹ̀" fún lílọ́wọ́sí ní tẹ̀le-ntẹ̀lé ìtàpásí òmìnira ẹ̀sìn, èyítí ó ńlọ lọ́wọ́lọ́wọ́, tí kò dára tí ó farahàn kedere, gẹ́gẹ́ bi a ṣe túmọ̀ rẹ̀ nípasẹ̀ IRFA:

- Wọnú àdéhùn kan tí ó l'ágbára, bí a ti ṣe fúnni ní àṣẹ lábẹ́ Ìpín 405 (c) ti IRFA, kí a sì pèsè àtìlẹyìn owó tí ó níiṣe àti ìmọ̀ràn, láti mú kí ìjọba Nàìjíríà gbé ìgbésẹ̀ pàtàkì láti kojú àwọn ìtàpásí òmìnira ẹ̀sìn,, èyítí ó ní nínú ṣùgbọ́n tí kò pin sí:
    - Mú ìdánilẹ́kọọ fún àwọn òṣìṣẹ́ ìjọba, awọn ológun àti ọlọpàá gbèrú lórí àwọn kíkojú ọ̀rọ̀ ìkórìíraa tí ó dá lórí ẹ̀sìn; dídáhùn sí jàgídíjàgàn ẹlẹ́yàmẹyà; jíjábọ̀ àwọn ìwà-ipá tí ó wáyé lòdì sí àwọn ẹlẹ́sìn; tí a sì ńfi ìyà jẹ àwọn ẹ̀ṣọ́ aláàbò tí a fì ẹ̀sùn kan wípé wọ́n lo ipá tí ó pọ̀jù àti ìpalára àwọn ẹ̀tọ́ ènìyàn miiran;

- Mú níní ààyè sí ìdájọ́ òdodo gbèrú àti kí ó fẹ̀si kí a sì ró àwọn ilé-ẹjọ́ tí kò sí fún ẹ̀sìn l'ágbára ní àwọn agbègbè tí àìní-ìfọ̀kànbalẹ̀ àwọn ẹléyàmẹyà ẹ̀sìn fí ẹgbẹ́kẹ̀gbẹ́ pẹ̀lú ìwà-ipá, wíwu ìwà ọ̀daràn, àti ṣíṣe ìdájọ́ àgbajọ ènìyàn ti ga..
- Mú gbígbé owó kalẹ̀ fún àtúnṣe ìpín ààbò àti ètò ìlànà tí ó bá òfin mu pọ̀ si, kí á sì jẹ́ kí àwọn olùkópa ilé-ẹ̀sìn lọ́wọ́ nínú ààbò àti àwọn ètò ìdájọ́ òdodo;
- Ya owó sọ́tọ̀ fún àwọn ètò tí yóò kó ọmọ ẹgbẹ́ tí ó ńjà fún ẹ̀tọ́ ọmọ ènìyàn, aláàbò, àti àwọn òṣìṣẹ́ ìjọba jọ ní akitiyan ìlọ́wọ́sí láti dáàbòbò àwọn ibi-ìjọ́sìn àti àwọn ibi mímọ́ miiran;

- Ṣe àtúnṣe tí ó kún ojú òṣùwọ̀n kan nípa gbogbo ìrannílọ́wọ́ oríllẹ̀-èdè Amẹ́ríkà sí Nàìjíríà àti àwọn ipa rẹ̀ lórí àwọn ipò òmìnira ẹ̀sìn ní orílẹ̀-èdè náà;
- Mú gbèrú àwọn ìlànà tí ó bá àwọn agbègbè mu kí a sì lo ìlànà òṣèlú láti bá àwọn aláṣẹ ìjọba ìpínlẹ̀ tí ó ṣe kókó pàdé ní àwọn agbègbè ní àwọn ìpínlẹ̀ tí ìlú fọwọ́sí tàbí faramọ́ àwọn ìwà-ipá tí ó wọ́pọ̀ láti mú àwọn ìṣe bá òfin oríllẹ̀-èdè àti àwọn ojúṣe ní àgbáyé mu;
- Mú àgbára ti ẹ̀ka tí ó ń sojú oríllẹ̀-èdè Amẹ́ríkà (U.S. Embassy) ní Abuja láti fèsì ní ìta gbangba sí àwọn ìdàgbàsókè sí àwọn ipò òmìnira ẹ̀sìn ní Nàìjíríà, èyítí ó ní sísọ̀rọ̀ lórí àwọn ẹjọ́ ní ilé-ẹjọ́ lòdì sí àwọn tí wọ́n wà lẹ́wọ̀n nítorí ẹ̀sìn ẹ̀rí-ọkàn wọn nínú, àti pẹ̀lú láti ṣe gbohùngbohùn àwọn ohùn nílé tí wọ́n ń ṣìpẹ̀ fún àwọn àṣà òmìnira ẹ̀sìn tí ó le.

### ÀWỌN IṢẸ́ & OHUN-ÈLÒ USCIRF TÍ Ó ṢE KÓKÓ

- Ìmúdójúìwọn  orílẹ̀-èdè: Ipò Òmìnira Ẹ̀sìn ní Nàìjíríà ní odún 2020
- *Ìwé òtítọ́ nípa:* Àìní-ìfọ̀kànbalẹ̀ Ẹ̀sìn àti àwon agbègbè Fulani ní  Ìwọ̀-oòrùn àti Àringbùngbùn Ilè-Adúláwọ̀
- *Iṣẹ́ nípa gbígbà Àwọn tí a fi sí ẹ̀wọ̀n nítorí ẹ̀sìn wọn wọlé* Mubarak Bala *àti* Yahaya Sharif-Aminu

## Àlàyé nípa ìrísí

Nàìjíríà ni orílẹ̀-èdè tí ó pọ̀jù lọ ní ilẹ̀ Adúláwọ̀, pẹ̀lú iye ènìyàn mílíọ̀nù 219. Láàrín àwọn wọ̀nyìí, ìdá 53.5 nínú ọgọ́rùn-ún ni a dámọ̀ bíi Mùsùlùmí, ìda 45.9 nínú ọgọ́rùn-ún bíi Kristiẹni, àti ìda 0.6 nínú ọgọ́rùn-ún tí wọ́n ń ṣe ẹ̀sìn mìíràn, èyítí ó ní àwọn tí kò gbàgbọ́ wípé Ọlọ́run wà, Baha'ism, Júù, Hindu, àwọn tí ó gbà Buddha gbọ́ àti Àwọn ẹ̀sìn àtọwọ́dọ́wọ́ ti àbáláyé nínú.

Ìwé òfin orilẹ̀-èdè Nàìjíríà ti odún 1999  ńdáàbòbò òmìnira ẹ̀sin tàbí ìgbàgbọ́, kò sì fi ààyè gba ṣíṣe ẹlẹ́sìnmẹ́sìn, tí kò dẹ̀ tẹnumọ́ ẹ̀sin kankan ní pàtó ti ijọba gbè lẹ́sẹ̀. Tí Òfin Ọ̀daràn Nàìjíríà náà tún ní ẹ̀wọ̀n tí ó tó ọdún méjì fún bíbú ẹ̀sìn ẹlòmíràn nínú. Ní àfikún, àwọn ìpínlẹ̀ méjìlá (12) ti àwọn Mùsùlùmí pọ̀ gan ní àríwá ńlo òfin ọ̀daràn Shari'ah àti ìdílé ní ẹ̀gbẹ́ kannáà pẹ̀lú àwọn òfin alágbádá àti ti àṣà; àwọn òfin ìfìyàjẹni Shari'ah kò fi ààyè gba ọ̀rọ̀ òdì.

Ẹ̀sìn ń kó ojúse tí ó l'ágbára nínú ìgbé-ayé l'áwùjọ àti òṣèlú ní Nàìjíríà. Àwọn ìyapa tí ó jinlẹ̀ gan-an nínú ẹ̀sìn àti àìgbara ẹni gbọ́ náà tún wà. Ní ọ̀pọ̀ ìgbà, àìní-ìfọ̀kànbalẹ̀ ẹ̀sìn ń fí ẹgbẹ́kẹ̀gbẹ́ pẹ̀lú ìdánimọ̀ ẹ̀yà, èyítí ó ń mú ìjà ẹ̀sìn eláyàmẹyà burú si nípa èyítí àti ẹ̀sìn àti àwọn ìpín ẹ̀yà tí a dámọ̀ wípé wọ́n ṣeé ń fà.

Ìjọba Nàìjíríà ń ja ìjà ológun lọ́wọ́lọ́wọ́ lòdì sí Boko Haram àti ISWAP ní ìlà-oòrùn àríwá orílẹ̀-èdè. Láì kà àwon ìjéwọ́ ìjọba àpapọ̀ sí wípé wọ́n ti ṣẹ́gun Boko Haram, àwọn ẹgbẹ́ wọ̀nyìí ṣì jẹ́ ewu sí àwọn alágbádá àti sí òmìnira ẹ̀sìn ní ẹkùn Lake Chad Basin. Àwon ìwàkiwà sí àwon ètó ènìyàn láti ọwọ́ àwọn olùkópa ti Nàìjíríà lòdì sí wíwu ìwà ipá tí mú ààbò burú jáì  tí ó sì fi àwọn ìgbé-ayé alágbádá sínú ewu.

### Àwọn ìkọlù sí Àwọn ilé Ìjọ́sìn àti àwọn ayẹyẹ ti ẹ̀sìn

Ní Oṣù kejì, àwọn alákatakítí Boko Haram kọlu Garkida, ìlú kan tí a mọ̀ bíi ìpìlẹ̀ Ìjọ Ará (Church of the Brethren) ní orílẹ̀-èdè náà, tí wọ́n sì sun ó kéré jù àwọn ìjọ márùn-ún. Ní àwọn ìkọlù ní tẹ̀le-n-tẹ̀lé ní ìpínlẹ̀ Kaduna ní Oṣù kẹ́ta, àwọn alákatakítí Fulani tí a furasí sun àwon ìjọ mérin. Ní Oṣù kẹrin, àwọn ti ó dira ogun tí a gbàgbọ́ wípé wọ́n ní àjọṣepọ̀ pẹ̀lú àwọn ọmọ-ogun ajìjàgbara Fulani kọlu ayeye ìgbéyàwó Kristieni ní Ìpínlẹ̀ Niger, tí wọ́n pa àwọn ènìyàn méjìlá (12) tí wọ́n sì gbé ìyàwó àt ọkọ lọ. Ní Oṣù keje, àwọn ènìyàn tí ó gbé ìbọn tí a kò dá mọ̀ pa àwon ènìyàn méjìdínlógún (18) ní àjọyọ̀ ìgbéyàwó Kristiẹni ní Ìpínlẹ̀ Kaduna tí wọ́n sì ṣe àwọn ọgbọ̀n (30) mìíràn léṣe.

Ní Oṣù karùn-ún, a jábọ̀ wípé àwọn mùsùlúmí afẹ̀míṣòfò kọlu agbègbè kan bí àwọn ènìyàn ṣe ń gbaradì láti sínu àwẹ̀ Ramadan wọn, tí wọ́n sì pa ó kéré jù àwon ènìyàn ogún (20). Ní oṣù yẹn náà, a jábọ̀ wípé àwọn ikọ̀ oní jihadi ti kolu ìlú Maiduguri bí àwọn ara ìlú ṣe ń gbaradi láti ṣe àjọyọ̀ Eid al-Adha ní Maiduguri, tí wọ́n pa àwọn ènìyàn mẹ́rin tí wọ́n sì ṣe àwọn mẹ́ta mìíràn léṣe. Ní Oṣù kẹwàá, àwọn ọ̀daràn tí a kò dámọ̀ mósálásí méjì ní Enugu ní gúsù orílẹ̀-èdè.

## Mùsùlùmí Alákatakítí Afẹ̀míṣòfò

Àwọn ẹgbẹ́ Mùsùlùmí alákatakítí ní àríwá Nàìjíríà ńtẹ̀síwájú láti gba agbègbè kí wọ́n sì ṣe àwọn ìkọlù tí ó le gan àti àwọn ìwàkiwà sí àwọn ẹ̀tọ́ ènìyàn ní ìlà-oòrùn àríwá Nàìjíríà àti ẹkùn Lake Chad Basin tí ó gbòòrò. Síwájú si, àwọn ẹgbẹ́ wọ̀nyìí ti fe agbègbè won sí ìwò-oòrùn, pẹ̀lú ISWAP nísìnyí tí ó ńṣe àwọn iṣẹ́ wọn ní Ìpínlẹ̀ Sokoto tí Boko Haram ńṣiṣẹ́ ní Ìpínlẹ̀ Kaduna.

Àwọn ọmọ-ìjà ISWAP jígbé tí wọ́n sì pa Ropvil Daciya Dalep, akẹ́kọ̀ọ́ ọmọ yunifasiti Kristiẹni kan, ní Oṣù kínní; tí wọ́n jí olùṣọ́-àgùtàn Kristieni kan gbé àti àwọn obìnrin méjì ní Ìpínlẹ̀ Borno ní Oṣù kẹwàá; tí wọ́n sì pa àwọn òṣìṣẹ́ arannilọ́wọ́ márùn-ún gẹ́gẹ́ bíi ìkìlọ̀ sí “gbogbo àwọn ti àwọn kèfèrí ńlò láti ṣe àyípadà àwọn Mùsùlùmí sí ẹlẹ́sìn Kristiẹni.” Àwọn ọmọ-ìjà Boko Haram jí Ẹni-ọ̀wọ̀ Lawan Andimi, alága agbègbè CAN ní Ìpínlẹ̀ Adamawa gbé, nígbàtí ó yá wọ́n bẹ́ ẹ lórí, nítorí ó kọ̀ láti sẹ́ ìgbàgbọ́ rẹ̀. Ní Oṣù kẹwàá, lẹ́yìn tí wọ́n ti dúnkokò nípa àwọn ìkọlù lòdì sí àwọn Kristiẹni ní ìgbà sáà Kérísìresì, àwọn ọmọ-ìjà Boko Haram ṣe àwọn ìkọlù mẹ́ta lòdì sí àwọn agbègbè Kristiẹni ní àríwá Nàìjíríà, tí wọ́n pa ó kéré jù àwọn ènìyàn méjìlá (12) àti jíjí olúṣọ́-àgùtàn Ìjọ ajínhìnrere kan gbé. Ní àfikún, ní Oṣù kínní, ẹgbẹ́ oní-jihadi Ansaru túnseyo ní Ìpínlẹ̀ Niger fún ìgbà àkọ́kọ́ lẹ́yìn ọdún 2013, tí wọ́n ńgba ojúṣe fún ìkọlù lórí “àwọn tí wọ́n sẹ́ ìgbàgbọ́ wọn” kan ní Oṣù kejọ.

## Àwọn tí a fi sí ẹ̀wọ̀n nítorí ẹ̀sìn wọn

Ní ọdún 2020, àwọn aláṣẹ ìlú tàpá sí ọ̀pọ̀lọpọ̀ àwọn ẹ̀tọ́ ọmọ Nàìjíríà sí òmìnira ẹ̀sin tàbí ìgbàgbọ́, àti pẹ̀lú nípa mímú fífi ìdímúlẹ̀ àwọn òfin sísọ̀rọ̀ òdì múlẹ̀ ní ẹgbẹ́kẹ̀gbẹ́ sí àwọn ọdún àtẹ̀yìnwá. Ní Oṣù kejọ, ilé-ẹjọ́ Shari’a ní Ìpínlẹ̀ Kano dá Yahaya Sharif-Aminu lẹ́bi sísọ̀rọ̀ òdì fún bíbú Wòlíì Muhammad ní ìfiránṣẹ́ WhatsApp ìkọ̀kọ̀ tí a sì dájọ́ ikú fún-un— nígbàtí ó yá ilé-ẹjọ́ gíga kan da ejó ìdálẹ́bi náà nù tí a sì pè fún tí tún ẹjọ́ dá. Àwọn aláṣẹ Kano tún rí ọmọ ọdún mẹ́rìndínlógún (16) Omar Farouk bíi ẹnití ó jẹ̀bi sísọ̀rọ̀ òdì tí a sì fi sí àhámọ́ ní gbogbo ọdún náà, bí ó tilẹ̀ jẹ́ wípé a da ìdálẹ́bi rẹ̀ nù ní ìbẹ̀rẹ̀ ọdún 2021 tí a sì tu sílẹ̀.

Ọlọ́pàá tún mu gbajúgbajà ajà fún ẹ̀tọ́ Mubarak Bala tí kò gbàgbọ́ wípé Ọlọ́run wà ní Oṣù kẹrin ọdún April 2020 lẹ́yìn àgbáríjọ tí àwọn agbẹjọ́rò ní Ìpínlẹ̀ Kano pe ìpẹ̀jọ́ kan tí wọ́n dáa lẹ́bi bíbú Wòlíì Muhammad nínú àwọn ìfìránṣẹ́ Facebook. Fún àwọn oṣù méjọ síi, àwọn ọlọ́pàá Ìpínlẹ̀ Kano State há Bala mọ́ láì pe ẹ̀sùn kankan, tí wọ́n ń dín níní ààyè rẹ sí ẹgbẹ́ agbẹjọ́rò rẹ̀ tí wọ́n sì kọ̀ láti pèsè ẹ̀rí ibití ó wà àti wíwà dáradára rẹ̀ fún ìdílé rẹ̀. Ní Oṣù kẹwàá, lẹ́yìn ọ̀pọ̀lọpọ̀ ìfàsẹ́yìn, ilé-ẹjọ́ ìjọba àpapọ̀ kan dájọ́ wípé híhá Bala mọ́ kò bá òfin mu tí wọ́n sì pàṣẹ ìtúsílẹ̀ rẹ—ṣùgbọ́n, ní bíi òpin ọdún 2020, Bala ṣì wà ní ọ̀dọ̀ àwọn ọlọ́pàá láìkà àṣẹ yìí sí.

## ÒFIN ORÍLẸ̀-ÈDÈ AMẸ́RÍKÀ TÍ Ó ṢE KÓKÓ

Ní Oṣù kejìlá ọdún 2019, Ẹ̀ka Ìpínlẹ̀ Orílẹ̀-èdè Amẹ́ríkà (U.S. Department of State) fún ìgbà àkọ́kọ́ fi Nàìjíríà sí Àkànṣe Àkójọ fún Ìwò (Special Watch List) fún àwọn orílẹ̀-èdè tí wọ́n tí lọ́wọ́sí tàbí farada àwọn ìtàpásí òmìnira ẹ̀sìn ní ọ̀nà tí ó burú jáì sí IRFA. Ní ọdún kan lẹ́yìn èyí, ní ọjọ́ kejì (2) Oṣù kejìlá, Ẹ̀ka Ìpínlẹ̀ Orílẹ̀-èdè Amẹ́ríkà (U.S. Department of State) ti pe Nàìjíríà gẹ́gẹ́ bíi orílẹ̀-èdè tí a ní àìbalẹ̀-ọkàn rípa rẹ̀, CPC, fún lílọ́wọ́sí tàbí fífi ara da ní pàtó àwọn ìtàpásí tí ó burú lábẹ́ IRFA, ìgbésẹ̀ tí USCIRF ti gbà níyànjú l’ọ́dọọdún láti ọdún 2009. Ṣùgbọ́n, ní àkókò kannáà tí ó wọ ìwé CPC náà, Ẹ̀ka Ìpínlẹ̀ Orílẹ̀-èdè Amẹ́ríkà (U.S. Department of State) gbé fífi ojú fòdá kan jáde lórí àwọn ìjìyà tí ó níiṣe bí ó ti ṣe nílò nínú “ohun tí ó jẹ àpapọ̀ ilú lọ́kàn tí ó ṣe pàtàkì ti oriílẹ̀-èdè Amẹ́ríkà,” ní ìbámu sí Ìpín 407 ti IRFA.

Fífún Nàìjíríà láti ọwọ́ Oriílẹ̀-èdè Amẹ́ríkà ńtẹ̀síwájú láti fi ìrànlọ́wọ́ ìgbélárugẹ ènìyàn àti ìdàgbàsókè ọrọ̀-ajé se pàtàkì. Ní Oṣù kọkànlá, Oriílẹ̀-èdè Amẹ́ríkà àti Nàìjíríà se ìgbanilálejò papọ̀ ìpàdé kan nípa ìṣọ̀kan lòdì sí Islamic State tí wọ́n sì ṣe ìjẹ́wọ́ ìfarajìn wọn sí ṣíṣẹ́gun Boko Haram àti ISWAP. Àwọn ipa àjọṣepọ̀ oriílẹ̀-èdè Amẹ́ríkà ní Nàìjíríà ní yíyanjú aáwọ̀ọ̀ ní àwọn ẹkùn tí wọ́n ńní àwọn ìpele ìwà ipá tí ó ga àti pẹ̀lú bíbójútó àwọn ẹjọ́ àwọn tí a fi sí ẹ̀wọ̀n nítorí ẹ̀sin wọn nínú.

Ní Oṣù kọkànlá, lẹ́yìn tí àwọn aláṣẹ ti Nàìjíríà wu ìwà ipá lòdì sí àwọn tí wọ́n ńfi ẹ̀hónú hàn ní àlááfíà sí ìṣìwàhù ọlọ́pàá, the Congressional Black Caucus fi lẹ́tà kan ránṣẹ́ sí Ààrẹ Muhammadu Buhari tí wọ́n ń bu ẹnu àtẹ lu ìwà ipá tí ìlú fọwọ́sí lòdì sí àwọn tí wọ́n ń fi ẹ̀hónú hàn pẹ̀lú àlááfíà láì wu ìwa ipá ní Nàìjíríà tí wọ́n sì ńpè fún àjọsọ ọ̀rọ̀. Àwọn asojú Texas, Al Green àti Joaquin Castro fi àbá kan lọ́lẹ̀ ní àtìlẹyìn àwọn tí wọ́n ńfi ẹ̀hónú hàn náà sí Ilé-ìgbìmọ̀ orílẹ̀-èdè Amẹ́ríkà.